# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE, TENI GBOGBO LA WA

No. 576 FRIDAY APRIL, 10 1964 (2D)


## Wosilatu Ju Ọmọ Rẹ Sinu Odo-Ọsa ?

ẸKO: – Ẹnu ya gbogbo ero ti nwọn pejọ si Ile ẹjọ kekere kan ni Yaba nigbati awọn Ọlọpa fi nhan ile ẹjọ na pe Iyaafin Wosilatu Adeoti ti şe ọmọ ọgbọn ọdun ngbiyanju lati ju ọmọ obinrin rẹ si inu odo Ọsa ni ọwọ awọn Ọlọpa fi tẹ ẹ.

Awọn Ọlọpa tun sọ pe bi Iyaafin Ọdaran yi ti ngbiyanju lati ju ọmọ rẹ Felicia ti işe ọmọ oşu mẹfa sinu odo Ọsa ni gbogbo awọn ero ti nkọja lọ ba fi igbe ta ti nwọn si tete sare yọ ọmọ na jade kuro ninu odo- Ọsa.

Irohin fi ye wa wipe Wosilatu tun ti ni oyun miran nisisiyi wahala oyun ti o ti ni yi lo fa ti o fi gbero ati le pa ọmọ ti o wa lọwọ rẹ bayi.

Adajọ ti sun ọjọ gbigbọ ẹjọ na siwaju, o si tun ti gba pe ki wosilatu lọ wa ẹniti yio şe oniduro fun un titi nwọn yio fi pari ẹjọ na,

Bi nwọn bati pari ẹjọ na si ẹ o tun ma a gbọ o.

# ẸJỌ AWO BẸRẸ LONI

ẸKO:— Ni deede agogo mẹfa irọlẹ ana ni awọn enia ti bẹrẹsi irọkẹkẹ kakiri gbogbo igboro ilu Ẹko ti nwọn si nsọ wipe ola ni ẹjọ Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ yio bẹrẹ ninu Ile-ẹjọ gigajulọ Eko, niwaju Ọlọla Adetokunbọ Ademọla ti işe Olori gbogbo awọn adajọ Agba fun Apapọ Ijọba Naijiria.

Onirohin wa kan fi ye wa wipe, awọn adajọ marun ni y'o joko gbọ ẹjọ Oloye Awolọwọ ninu Ile-ẹjọ na ni owurọ yi.



Ọlọla Ade. Ademọla

Orukọ awọn adajọ Agba na ni: Ọlọla Loius Mbanefo, Olori gbogbo awọn adajọ Ipinlẹ Ila Orun Naijiria, Ọlọla John Idomora Conrad Taylor, Ọlọla Vale Bairamian, Ọlọla Lionel Brett, gbogbo wọn ni yio jẹ oluranlọwọ fun Ọlọla Adetokunbọ Ademọla ninu Ile ẹjọ gigajulọ na loni.

Ninu Ile ẹjọ na lana, Oniwe Irohin wa Ẹjon'gbo-



OLOYE ỌBAFẸMI AWOLỌWỌ

ro fi ye wa wipe on ba Ọgbẹni M. A. Ọdẹsanya ọkan ninu awọn agbẹjọro awọn olujẹjọ na pade ti o nfun awọn oşişẹ Ile ẹjọ giga na ni iwe kan.

A lero pe ara awọn iwe t nwọn o fi şe ẹjọ na ni



Ọgbẹni Ọdẹsanya

owurọ yi ni Ọgbẹni Ọdẹsanya mu lọ si Ile ẹjọ na.

Oniwe irohin na tun fi ye wa wipe, awọn Ọjọgbọn Oloye, Amofin meji, Ọgbẹni Victor Durand ati Ọgbẹni Thomas Killock ni nwọn ti de si Eko ninu ọsẹ yi, lati wa gbẹnuuşe fun Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ.

Awọn agbẹjọro mejeeji yi ti fi orukọ wọn silẹ ninu ile ẹjọ Eko gẹgẹbi ẹniti o ni aşẹ lati le şe ẹjọ ninu Ile ẹjọ giga Eko.

A si gbọ wipe Ijọba ti gba fun Oloye Awolọwọ lati gba agbẹjọro ti o ba wu lati Ilẹ Okere.

Oniwe irohin wa fi ye wa wipe awọn Ọjọgbọn Amofin na wa si Ile ẹjọ na ni ana.

Irohin kan ti a gbọ ni abẹ lana, şugbọn ti a ko ri ẹ u fi ye wa wipe, Ada-

(Wo Oju Ewe Kẹfa)



Ọgbẹni J. S. Ọlawọyin



Ọgbẹni Latifu Jakande



Ọgbẹni B. Adedipẹ

# IROHIN IMOLE

ẸSIN ỌRỌ WA-IMỌLẸ ỌRẸ AIYE, TẸNI GBOGBO LAWA
Ẹ kọwe si:— OLOTU IROHIN IMỌLẸ
FUN OWO IROHIN IMỌLE ỌDUN KAN
PỌNUN MEJI ṢILE MEJIA (52/—)

## ỌRỌ OLOTU

## Ki O Ri Fun Nyin, Bi Igbagbọ Nyin

Nigbati Jesu wọ inu ilu Kapanumu, lati ma a wasu ihinrere, ọpọlọpọ awọn enia lowa si ọdọ rẹ lati wa gbọ ọrọ rẹ awọn miran ti nwọn ni orisirisi arun, ti nwọn fe imularada Jesu si mu gbogbo wọn ni ara da, nwọn si fi ayọ pada lọ si ile wọn.

Ṣugbọn Balogun Ọrun tọ Jesu wa, o si bẹ e wipe, Oluwa, ọmọ-ọdọ mi kan dubulẹ aisan ẹgba ni ile, ọmọ ọdọ na si ni irora pupọ, Jesu wi fun un pe, Emi mbọ wa mu ọmọ-ọdọ na larada ninu ile rẹ.

Balogun Ọrun na dahun, o si wipe, Oluwa, emi ko yẹ ni ẹniti iwọ iba fi wọ abẹ orule mi, ṣugbọn sọ kiki ọrọ kan, ao si mu ọmọ-ọdọ na larada. Ẹniti o wa labe aṣẹ sa li emi, emi si li awọn ọmọ-ogun lẹhin mi, bi mo ba wi fun ẹnikan pe, Lọ, asi lọ, ati fun ẹnikeji pe, wa, asi wa; ati fun ọmọ-ọdọ mi pe, ṣe eyi, asi ṣe e,

Nigbati Jesu gbọ, ẹnu ya a, o si wi fun awọn ti o nto ọ lẹhin pe, looto ni mo wi fun nyin, Emi ko ri igbagbọ nla bi iru eyi ninu awọn enia Israẹli.

Mo si wi fun nyin, ọpọlọpọ enia ni yio ti Ila-Orun ati iha Iwọ-Orun wa nwọn a si ba Abraham ati Isaaki ati Jakọbu joko ni ilẹ-Oba ọrun, ṣugbọn awọn ọmọ ile ọba li ao sọ sinu okunkun lode, nibẹ ni ẹkun on ipahin keke yio gbe wa.

Jesu si wi fun Balogun Ọrun na pe, Ma a lọ bi iwọ ti gbagbọ, bẹni ki o ri fun ọ, a si mu ọmọ ọdọ re na larada ni wakati kanna, gẹgẹbi igbagbọ Balogun Ọrun na

Ninu iwe wa ọjọ kẹjọ oṣu yi, ni a se irohin awọn ọmọ ẹgbẹ Odudwa ẹka Ipinle Ila Orun Naijiria si, nibi ti nwọn ti se ipinnu wipe awọn yio gba Aawẹ ọjọ mẹta, eyiti awọn ọmọ ẹgbẹ na yio bẹrẹ ni owurọ yi.

Awọn ọmọ ẹgbẹ na ṣe ipinnu yi ninu ipade ti nwọn ṣe, pe awọn ni igbagbọ ti awọn ba gba Aawẹ ọjọ mẹta pẹlu akanṣe adura Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ yio bori ẹjọ re, ti Ijọba mbaa ṣe, eyi ti bẹrẹ ni owurọ yi le'Eko.

Awọn enia na ni, awọn yio tun gba adura fun awọn adajọ ati awọn agbẹjọro ki Ọlọrun le ṣe aṣiwaju ati ikẹhin wọn ninu ẹjọ ti nwọn yio bẹrẹ ni Eko ni owurọ yi.

Ko si ẹbọ kan ti ole, ti adura ko le mu lo, bi okeiṣoro kan ti wulẹ ki o le to awọn ọmọ ẹgbẹ na ni adura lo le mu si sọlẹ. Nwọn si kesi gbogbo ara ilu lati ṣe iranlọwọ fun wọn lati ba awọn gba adura na.

Ẹjọ Oloye Awolọwọ yio bẹrẹ ninu Ile ẹjọ gigajulo ni owurọyi, awa oniwe Irohin Imọlẹ wa kesi gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ Odudwa ati awọn ara ilu ti wọn o bẹrẹ aawẹ ati adura ni owurọ yi pe, "Ki o ri fun nyin gẹgẹbi igbagbọ nyin," ki Ọlọrun ki omu gbogbo imọ nyin ṣe.

Ẹ ku ongbẹ o.

# Ijala Are Ọdẹ

Lati Owọ A. O. ADENIYI

Gẹgẹbi mo ṣe sọ fun nyin pe igo sọ itan ti Ọgbẹni Ọladipọ Yemitan sọ lori Ọdẹ ile-Aiye ati t'ọrun, iwe na fi han wa pe Wara ni Ọdẹ ile-Aiye, Olugbuele l'ọde ode ọrun o si tun fi han wa wipe iwa ọdalẹ ko sunwọn.

Bi ẹba ti nka ọrọ mi yi lọ ẹo ma ri bi o ti se jẹ ninu Ijala na :-

Wawa l'ọdẹ ile-Aiye.
Olugbuele l'ọdẹ ode ọrun
Awọn l'o kọkọ da Ọdẹ silẹ
ni ijọun.
Ẹran ni wọn ma pa kiri;
Ijọ ti nwọn yio da lẹ si
ara wọn
Ni nwọn pade lodo.
Nwọn ri ẹja t'opọ l'odo yi,
Nwọn da Ijọ ti nwọn yio
gbo'do
Igbati ọjọ ku ọtunla,
Wawa ti se ọdẹ ile aiye
Yọ re ji odo gbọn,
Wawa re yọ ilẹ da
Oni'le ori oke tenre,
Oni'le ori oke tenre
Ogun jẹ ng rọmo pe ran
nṣe,
Onile ori oke tenre,
Bi iwa ọdalẹ ko ti dara to,
Odo ti nwọn ba ẹja pupọ
ninu rẹ tele
Ẹja ẹyọ kan soso ni Wawa
ri pa!

Bi ẹba ti ra iwe yi ti ẹ si ka ẹo ma gọọ bi gbogbo rẹ se nlọ.

Siwaju si ninu Iwe rẹ Ọgbẹni Yemitan tun fi ye wa nipa Ogun Onire

Bi mo ti ṣe sọ fun nyin saju pe Oje asa fun awọn ọdẹ lati ma ṣe apọnle Ogun Asi tun gbọ pe ilu kan ni wọn pe ni Ire ni ilẹ Yoruba, nibẹ ni ati gbọ ti nwọn kọ wipe:-

Ẹni ba ko'yan ko yara
ko togun silẹ
Ẹni ba roka ko yara ko to
gun silẹ
Ogun onire, ọkọ mi, Iyakan
agbolu irin
Ajangbodo erigi, koriko
odo ti Iru mini-mini.
Awọn Asiwere enia lo ni
b'o gun ba lẹ sodo.
Awọn yio ma lọ oko igi,
Nwọn o ma p'orisa ti igba
'lẹ gb'odo.
T'o le gba oko igi lọwọ
wọn ni.
Ẹbẹ l'emi mbẹ erigi l'ọgbin
Pe k'o ma gba le gbodo.
K'o ma gb oko igi da,
Ogun ni gi an bi igi da,
Ogun ni elewele ọkunrin,
Iku ti fori ja, ti i fi iru ja.

Bi ẹ ba ka Ijala na lọ titi, ẹo ri ka pe Ọsọsi lorukọ aya Ogun, ti o ba wọn da Ọdẹ silẹ ti ko le sọdẹ.

O tun fi han wa siwaju si pe, meje ni ire, meje ni Ogun ọtọ ni Ogun Onire Sambebe, ogun kan kọ ile arọ, ọkan o ho le aro ọkan yọ odẹdẹ imọ, ọkan ko yọ odẹdẹ imọ.

Siwaju si i, lẹsẹ ti mbọ yi, ngo tun ba nyin sọrọ lori Ijala ti Ọgbẹni Yemitan kọ lori awọn ọmọ Ogun.

Ẹ ma salai ra iwe na, "Ijala are Ọdẹ, ṣile mẹrin din tọrọ ni nwọn ta ni gbogbo ile ita iwe wa.

## Iwọ Ha Nlọ Si Mẹkka Ni Ọdun Yi Bi?

"ALAMU LABEKA ALAMU LABEKA"
MO JẸ RI O, OLUWA MO JẸ IPE RẸ
Ẹnikẹni ti o ba fẹ lọ si "MẸKKA" Ilu Mimọ ni ọdun yi gbọdọ ni iwe

"AFINIMỌNA NPA ISIN HAJI"
LỌWỌ KI OLUWARẸ MA BA ṢINA TABI NA OWO INAKUNA. KI O LE LỌ ALỌBỌ MẸKKA NA DADA
t'Oluwa jọwọ se Isin Haji wa ni eyiti o tọna. Si jọwọ fun wa ni rere ti aiye ati t'ọrun Oluwa wa. ki o sisọ wa ni bi iya nitori IWỌ NI ỌBA alagbara Olubori gbogbo ẹda patapata" Amin

"WAS SALAM"

*AKIYESI* Gbogbo Musulumi Ododo ri oyẹ ki o ni iwe na lọwọ nitori igbati yio ba fẹ lọ si MẸKKA
*Iye Owo 5/6, £3 fun dosini*
MANAGER
N2/99 SITTU STREET
Hlbadan

# IWE SI OLOTU

## Shagamu Nfę Atunșe Ijọbg

Inu mi yio dun bi Olotu Iwe Irohin Imọlę ba le gba mi laye lati kesi awọn alașę Ijọba Ibilę ati papajulọ Ijọba Ipinlę Iwọ Orun Naijiria pe, ki nwọn jọwọ ki nwọn ba wa tun gbogbo awọn oju titi ti o wa larin awọn ilu Shagamu șe nitoripe awọn oju ọna na ko dara mọ nisisiyi ki nwọn si ba wa da ọda si gbogbo ibiti o ti baję.

Abuku nla lo jẹ lati ri wipe awọn oju ọna ti a kọja ni Shagamu ko dara to, o si jẹ ohun itiju fun awa ọmọ ilu nigbati awọn alejo pa de ilu na.

O ti to ọdun mejila ti nwọn ti șe awọn oju ọna na nisisiyi o si ti mu ọpọlọpọ anfani wa fun awọn enia.

Atipe lati igbati nwọn ti șe oju ọna, ọna Shagamu ni gbogbo awọn mọto ngba nisisiyi, nwọn ko gba ọna Abeokuta mọ.

Nitorina, inu gbogbo awa ọmọ Shagamu ni yio dun ti Ijọba Ibilę ba le șe iranlọwọ na ki nwọn si yọ ọda si awọn oju titi na ki asiko ojo to de.

Olotu, mo dupę aye ti ę gba mi o.

Emi ni,
OLUȘEYI PEDRO,
Shagamu.

## Ę La Ęyi Ye Wa

A gbadun iwe pęlębę pęlębę ti Ọgbęni Hubert Ogunde ati awọn elere rę șe ti nwọn nta ni șile meji, (2/-) o to asiko ti o yę ki "Yoruba Ronu" wọn, awọn na ni ana ati loni, ę jẹ ki a ronu lati pa awọn iwa ti ko dara ti, ki a ni ifę si arawa.

Pataki ọrọ mi ni ọrọ ti o wa ni oju ewe kęfa, Oba ilu kan la ala ti o ba lęru pupọ ti o fi kesi babalawo lati wa ba on yọ ala na wo. Babalawo na ni edealumọ lodifa fun Olu—Ipo gbę ko rubọ.

A fę mọ Olu—Ipo ti Ọgbęni Ogunde ndarukọ ninu iwe na. Nitoripe Ogun ko ja Olupo ri rara, inu wa yio dun bi Ọgbęni Ogunde ba le fi ọrọ na ye wa yekeyeke, nitoripe o ti da ija silę larin awọn ara ilu miran ati ilu wa.

Nitorina ọrọ re o, a nfę mọ Olu-Ipo na o.

Olotu Ọlọrun yio bo asiri nyin.

Emi ni,
KARIMU AJENIFARI
Ajassę—Olupo

## Ę Ko wa Irępọ

Olotu ę gba mi ni aye dię ninu iwe nyin ti nkọ wa ni ọgbọn ati oye lati ba Ijọba Ipinlę Iwọ Orun sọrọ lori ọrọ kan ti gbogbo wọn nsọ pe, awọn nfę irępọ, awọn nfę isọkan ati nwọn ko hu iwa isọkan ati irępọ rara, awọn olorin ni ti a ba le ni ti a ko ba le ba ni iwọn ni a șe aalọ mọ. Kișę tulasi ni enia fi șe ęgbę oșelu, ọranyan ku sidi rę ni

Ę ni ę nfę Isọkan ati irępọ larin awọn ọmọ Yoruba ni akọkọ ę gba oye ti nwọn fun Alhaji Adegbenro Ęnyin Ijọba kan na ni ę fun Oloye Awolọwọ ni oju ọna meji lati mọ pe ni orukọ rę ati Oloye Anthony Enahoro ati awọn yoku.

Ęyin kanna ni ę tun npa orukọ na da, nigbati ę nsọ, nwọn di nyin loju ni bi? Nigbati ija de torin di owe, ę tun gbogbo rę yi.

Ni Ọgbęni Kọla Balogun ko ba ęgbę Dęmọ lọ mọ, ęgba oye ti o tọ si, Ijọba ti Oloye Awolọwọ nșe olori rę lọwọ ati ęsę si, ę si ni ę nwa irępọ ki a mọ tan arawa jẹ a kole kęgan Ọlọrun, gbogbo iwa ti ę nhu yi nfi han pe, ęko wa isọkan ọmọ Yoruba kaka ki a jẹ ekuru ki o tan ę tunngbọn ọwọ rę sinu awo

Ti a ba ti fi iwa adi rę da ni logun nu mo fọ lęy,n silę ilę wa ko le toro rara.

Mo dupę Olotu fun aye ti ę gba mi

Emi ni
IJAKODỌLA
Ile-Oluji


# AKARA TU S'EPO!

## Iwe Itumọ Ala na ti de!!

Eyi ni lati kede fun awọn onkawe Irohin Imọlę pe Iwe Itumọ Ala lati ọwọ Joseph Alala ti jade fun tita nisisiyi. Iwe Ala yi yatọ si Iwe ala miran nitoripe Odu Ifa ni awọn fi tumọ rę Egbogi jaburata si wa ninu rę pęlu. Tete ra tirę ki o to tan.

Iye Owo:— Iwe kan 5/-
Dọsini 36/-

J. O. SHOYINKA
N/99 Shittu Street
Ibadan



# Kere o!

Fun anifani gbogbo ęnyin onișowo, Iwe Irohin Imọlę yio șe ipolowo awọn ọja nyin fun nyin ni ọsę kan gbako ki ọdun Ileya o to de ati lehin ọdun ki awọn onibara nyin le ba nyin ra ọja ti ọdun Ileya ti mbọ yi.

Awọn Așoju wa yio ma a lọ kakiri lati bere fun awọn ti o ba fę lati polowo ọja wọn ninu Iwe Irohin wa.

Owo pọọku ni a ngba, dan wa wo lękan ki o ri bi ajo rę yio ti ta to, Ijafara lewu o.



# Congreves' Female Remedy

(FUN OBINRIN)

Ojulowo egbogi titun fun gbogbo awọn Obinrin ti o ba ni iyọnu tabi amodi Inu rirun nigbakugba tabi ni ękọọkan ęhin-didun, ibadi-wiwo tabi sisan ejędudu ara tabi aikotọ ęję lara Inu gbigbona nigbakugba Igba — aiya riru ọmu riro, didun arę atinu wa ti oma nfa oyi-oju Ilaogun ara ęsę ara sisọn, ęfọri abi pęlu iba ati otutu Egbogi yi dara pupọ julọ fun itọju gbogbo Obinrin gegębi Ajo fun ilera ati orișirisi amodi miran ti o ma nyọ wọn lęnu ni ni nigbakugba pęlu.

(OLOMI IGO NLA NI)

BERE EGBOGI ATI JỌ TI WỌN NPE NI:-

## Ammoniated Quinine Tincture

Nigba lailai ki awọn Orișirisi rọbirọki egbogi ti wọn nko wa nisisiyi to de awọn agbalagba aiye atijọ mọ daju wipe kosi ohun ti a le fi Iwe egbogi yi bi otutu ikọ iba, orerę lukuluku onigbameji ti a ipe ri nyọ enia lęnu yala Ọmọde tabi agbalagba ni yio șe iwosan rę bi danga ni bi oba ti ta dię sinu omi ti o lọwọrọ ki o si gbemu bere egbogi ti o daju fun itọju eti riro tabi didun, ati Akokoro, egbogi ti o ma nfọ opo-ile-itọ tabi se iwosan iyọnu apo-ile-itọ egbogi aju didun tabi ti ọwa-ọfun didun, ati orișirisi omira pęlu wọn mbę ni șọbu awọn :—

Waterloo Medicine Stores,
8, PalmChurch Street, Lagos.
Phone:h Nigeria, (Ọja Ita Faj)



# BI O BA NI

# Iwe—Titę

*FUN*

**Lilo nibi Ișę rę tabi orișirisi iwe itufọ tabi ijade Oku**

*ATI*

## Iwe Igbeyawo

TETE KỌWESI ILE—IȘĘ ĘRỌ—ITĘWE

**Modupę Printing Press**

16, Bamgboșe Street, P. O. Box 1495
Telephone: 21985, Lagos.

KETEKETE NI ĘRỌ ITĘWE WA NHAN
*OWO PỌKU NI A SI NGBA*

IROHIN KO TO AFOJUBA
*Dan wa wo lękankoșo ki o si ri iyatọ*

# Adajọ ṣe Abẹwo Ibiti Mọto Ṣẹgun ti ṣe Ijamba

IBADAN:— Ni ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹfa oṣu yi ni adajọ agba Ọgbẹni Shomolu ṣe abẹwo sibi ti ologbe Ṣẹgun Awolọwọ ti ko jamba mọto ni ọjọ kẹwa oṣu keje ọdun to kọja ni ọna Ibadan si Eko. Nigbati ile ẹjọ kan bẹrẹ ẹjọ apania ti wọn fi ẹsun na sun Rashidi Ayinla fun iku Ṣẹgun ti mọto rẹ kọlu tirẹ lojiji.

Ninu ọrọ Rashidi o si sọ pe pe o si nwa mọto ti on ni apa ọwọ ọtun ati pe nigbana wọn si nṣe atunṣe ọna to fi jẹpe nwọn si ti apa kan ọna na pa fun awọn awa-mọto.

Gẹgẹbi ọrọ agbẹjọro fun Rashidi, Ọgbẹni Okuribido to si jẹ agbẹjọro si sọ pe Rashidi si ri mọto Ṣẹgun fun igba ekini ni bi nkan bi ọgbọn ẹsẹ sẹhin pẹlu are to ga.

Rashidi si tun sọ ninu ọrọ rẹ pe on si wa lori are to fi jẹ pe ogun iibusọ ni on nsa fun wakati kan pe on kọ tifi gba kan sa sare to ọgọta ibisọ larin wakati kan gẹgẹ bi agbẹjọro fun Ijọba Ọgbẹni A k i n Apata ti sọ ninu ọrọ rẹ.

Ẹ o ma gbọ ẹjọ na ti nlọ si ti ẹ ba nka iwe Irohin nigba gbogbo.

## ★ YẸ IRAWỌ RẸ WO ★

AQUARIUS (Jan 21 - Feb 18) Ọkan rẹ le daru loni, ṣugbọn ire ni igbẹhin rẹ yio jẹ, wahala inu ile yio si gba ọ ni aseko maṣe jẹki ẹru ba ọ rara.

PISCES (Feb 19 - Mar 20) Maṣe ṣiṣẹ pakanle ke kan loni, nṣe ni ki o lọ dubulẹ ki o sun, pa gbogbo ibinu ọkan rẹ mọlẹ gbe ọkan rẹ kuro ninu wọn ohun ti ko le ṣanfani ki o ma ba fa ijọ gbọn.

ARIES (Marh 21 - April 20) Anfani rere kan yio wọle tọ ọ wa loni ẹni kan yio gba ọ nimọran rere kan ti yio ṣe ọ ni anfani

TAURUS (Apl 21 – May 21) Iwa rere ti o ti nhu yio ṣe atilẹhin ire kan fun ọ loni. Eyiti ọkan rẹ ba yan fun ọ ni ki od mu. Are ọkan yio mu ọ ni ọwọ owuro, sugbọn idaraya yio wa fun ọ ni ọjọrọ.

GEMINI (May 22 - Jun. 21) Alejo rere kan yio kan ọ lare loni, ṣugbọn maṣe jẹki ọkan rẹ ro irokiro rara. Maṣe bere nkan titun loni

CANCER (June 22 – July. 21) Jẹki ohun ti oba gba lero je itẹlọrun ọkan rẹ, ara rẹ yio ya gaga ni akoko ọjọrọ bi o ba lọ tọju ara rẹ.

LEO (July 23-Aug 23) Nipa ọrọ kan ti ẹnikan yio sọ fun ọ, o yẹ ki o mọ iru ọrọ ti o yẹ lati da si, inu rẹ yio dun loni, maṣe jẹki ija onija di tirẹ ẹsọ di ọwọ rẹ.

VIRGO (Aug 24-Sept 23) Inu gbogbo enia yio ma dun si ọ loni ohun gbogbo yio si ma dọgba fun ọ sa ṣe jẹje, oni yi dara fun ọ.

LIBRA (Sept 24-Oct 24) Inu rẹ yio dun si iwa ti gbogbo enia yio ma hu si ọ loni, ohun ti gbogbo enia ba nṣẹ loni ni ki o ma ba wọn ṣe.

SCORPIO (Oct. 24-Nov. 22) Ẹlẹgbẹ rẹ kan yio sọrọ rẹ ni rere loni inu rẹ yio dun jọjọ si ọrọ na, maṣe ba awọn alabagbe rẹ ja, ki osi ma ṣakiyesi awọn ọrọ ti o nsọ, ki o ma ba sọọboti.

SAGILTANIUS (Nov 23 Dec 21) Alafia ati ara lile yio wa fun ọ loni, gbogbo isesi rẹ loni, yio tẹ gbogbo enia, maṣe ṣe agba osika ti ndijọ apakan.

CAPRICORN (Dec 22-Jan 20) Iwọ yio da iṣẹ kan silẹ loni, maṣe jade lọ sibikan lalẹ oni, bikoṣe pe ki ojoko nile tabi ki o lọ sun

# Igbimọ Atunto Ẹgbẹ Imọlẹ Aiye

GẸGẸBI ati fi aṣẹ fun mi lati ọdọ awọn Igbimọ atuneto ẹgbẹ Imọlẹ Aiye pe, awọn ti tu ẹgb Imọlẹ Aiye tẹlẹ ka, a si ti tun da omiran silẹ n torina ti o ba ri pe o fẹ jẹ ọkan ninu ọmọ ẹgbẹ tẹ tun yi ki o kọwe si mi ki o si ri pe o wa si Ipade ni ọjọ kọkanla oṣu kẹrin (11/4/64) ni dede agogo mẹta ọsan.

Ẹgbẹ yi yatọ si ti atẹhinwa a si tun ti ni ofin titun miran, Eyi si ni awọn ere ti ẹgbẹ titun na yio ma

1. Lati maa kọ awọn ọdọ ilẹ yi ni ọnab a ti nkọ irohin, itan, ọrọ sinu iwe Irohin la i ọdọ awọn Ọjọgbọn oniwe Irohin.
2. Ere bi Bọọlu alafẹsẹ gba, Table Tennis, Swimming, Entertainment, Ayo. Iṣẹ, Draft Ludo Picnic ati ọpọlọpọ awọn nkan miran ti ẹo ma a gbọ ni ipade.

Nitorina ti o ba fẹ tun jẹ ọkan ninu awọn ọmọ ẹgbẹ, titun yi ki o wa si ipade ni ọjọ 11/4/64 ni nọmba lẹ Bamgboṣe St., Lagos, Ao si tun yan awọn alaṣẹ ẹgbẹ titun.

Eyi ni orukọ awọn Igbimọ atun to ẹgbẹ Imọlẹ:—

J. Ọla. Okunlọla
Latifu Babalọla
Sedu Olupo
Abudulai Awẹlẹnjẹ
Timothy Akins

Ẹ jọwọ ẹ tete de ipade o.


# Iboosi Ikọ Ti Ọjọ Rẹ Ti Pẹ Lara

Awọn Egbogi Rọbirọbi ti wọn nta kakiri Igbor joko le ṣe Iwosan wọn lailai afi ki o ri ojulowo Egboo ilu ko ti o ba lagbara gidigidi lati le hu Ikọ na lati ibgi "Ikọ" si ti o si ti gbilẹ Fun awọn iru Ikọ bẹ yẹ iti oti bere fun egbogi wọnyi:

## "Thmo-Ephedrin" Tabi Egbogi 'Linituss'

Fun iwosan ikọ Asima, ikọ fere ikọ otutu igba-aiya ikọ Igbẹdu, ikọ-ọnafun, ikọ-gbigbẹ tabi eyiti o ma nmu ki enia ma ha ọna-ọfun tabi pẹlu kẹlẹbẹ tabi ti o ma njẹ ki enia ru nipa wahala tabi aikoni le sun daradara lọsan ati oru-ọbiyanju lati dan ọkan ninu awọn egbogi alagbara gidigidi wọnyi wo fun ara rẹ iwọ yio si ri iyatọ gburugburu larin wọn si awọn olomi ṣorokiti ti wọn nta kakiri.

O daju nibẹ iwọ yio bẹrẹ si ri alafia, iwọ yio ma jẹun daradara wasi ma sun fọnfọn pẹlu Alafia de si ọ ni yẹn Bere ni Ṣọbu awọn:—

Bere egbogi ajẹbina Richelet y'ni ṣọbu awọn

Waterloo Medicine Store
8, Plamchurch Street, Lagos
Phone:-2787 Nigeria, (Ọja ita Faji)

(2) Adedun Chemist
4 Wakeman Street, Yaba


# Ẹ ma ka Irohin Imọlẹ lojojumọ

# Ẹsin Islam Lo Peju

LATI ỌWỌ SALAWU-DEEN, OMUPỌ

Asalatu fuu Anabi Muhammad wa ati ọpọlọpọ ọpẹ fun Oluwa, Ọrọ mi ti ọsẹ yi duro lori ọna ti "ẹsin Isilamu fi pe ju" ati pe ohun nikan ni Ọlọrun yọnu si julọ.

Kurani ori 5 ẹsẹ 3, sọ bayi pe o si yi ni mo pe ẹsin nyin fun nyin mo si se aṣe pe ore fun nyin, mo si tun Yọnu si Isilamu fun nyin gẹgẹbi ẹsin atipe Isilamu nkọ wa ni Ijọwọ ara ẹni lọwọ fun ofia ati ihuwa rere si ẹda enia.

Aya yi fi kọ wa pe, ẹsin Isilẹmu ni Oluwa tilẹ tun sọ nibomiran pe, ẹnikẹn to ba tilẹ fi ẹsin Isilamu silẹ lati mọ sin gbogbo irun yi to ba tilẹ tun sin Oluwa ko ni gba, Oluwa sọ pe Oluwarẹ ati esin to ba sin eleyi Isilamu ofo ni Oluwarẹ yio ṣe lọrun.

Wo kurani ori 3 ẹsẹ 85, sọ bayi ẹnikẹni to ba wa omiran sẹ lẹhin ẹsin Isilamu, Oluwa ko ni gba ẹsin oluwarẹ to ba di lọrun ofo ni ẹni na yio se.

Kurani ori 2 ẹsẹ 112. Dajudaju ẹni to ba jọwọ ara rẹ lọwọ fun ofin Ọlọrun ti o si nṣe rere Oluwarẹ yio san Oluwarẹ ni ẹsan rere, eru ki yio ba wọn nwọn ki yio banujẹ.

Oluwa lo ti kalararẹ so ẹsin Isilamu ni oruko wo kurani ori 22 ẹsẹ 78, sọ bayi, On Ọlọrun ni o sọ nyin ni Musulumi ni atetekọse ati nisiyi, nitorina eleyi fi han wa pe, Musulumi lo tẹle ofin Ọlọrun.

# Ọdẹ afi fila pa Ẹrin, Ọjọ kan Ni Iyi Rẹ Mọ

Lati ọwọ BABA ẸSỌ, Apapa—Ajegunlẹ

Nigba laelae ni Ile Ifẹ, akọ Ẹkun kan ja wọlu gbogbo ilu daru, nwọn nrọ gidigidi sọtun ati si osi, irohin gba ilu kan pe Ẹkun na pa Lagbaja o pa Tamẹdu. o si pa Lakaṣegbe.

Gbogbo awọn Ọdẹ lo hamọra pẹlu ibọn wọn, bẹni iro ibọn ndun lọtun, ti o ndun losi nṣe ni ẹkun yi ṣa npa gbogbo awọn ọdẹ ti o ba yinbọn si. Ẹkun yi sede ẹnikan ko le ta ọja ẹnikan ko si le jade lọ ra oja bẹni ebi npa gbogbo enia ati Ọba ati Ijoye.

Ọkunrin Agbẹ kan ẹniti o ti mbẹ ni oko fun ọpọlọpọ ọjọ dakan wa bẹ ilu wo Nigbati o wọ ilu kosi ẹniti o le jade si ode. Bi o ti nla arin ilu lọ bẹni o pade Ọdẹ kan ti o nyọlẹ.

Agbẹ na kesi ode yi o bere wipe eṣe ti gbogbo ilu fida kese bayi? Ọdẹ na fesi wipe Alejo ha ni iwọ nileyi bi? Nje iwọ ko ha gbọ wipe Akọ Ẹkun nbe nigboro ilu wayi bi o ba pẹju ni lẹnu o kan o lara tan Agbẹ na leri pe lọjọ ti on ba fi oju kan Ẹkun na, lọjọ na lo ri aiye mọ

Nigbati Ọdẹ na gbọ bayi, o ni ki Agbẹ na kalọ si awujọ awọn Ọdẹ Laifa ọtọ gun bi Agbẹ na ti foju kan Ẹkun yi, O ṣi fila ori rẹ, ojan mọlẹ o wipe Ọbẹrẹkẹtẹ.

Ẹkun na fo soke o fori sọlẹ o si ku bamubamu ariwo ta ge gẹgẹbi aṣa awọn Ọdẹ bi ẹnikan ba pa Ẹkun nṣe ni gbogbo awọn ọdẹ ni lati yin bọn wọn danu.

AH! REMEMBER THAT

**The Social Dandies**

*PRESENTS*

**An Eid-Ul-Kabir Dance**

AT

**FORSTER CENTENARY HALL**

22, Ọdunlami Street, Lagos. On Sunday 26th April 1964 (Sunday Ọdun Ileya) at 6 p. m. till dawn

*Music by one and only*

NEW TIME TAPE RECORDING BASHY & HIS YOUNG STARS ORCHESTRA

Ladies and Gents, seize this opportunity and come and listen to the latest beats of Roy Chicago, Eddie Okonta, I. K. Dairo M. B. E., Broadway Dandies of Ghana on the New Time Recording Enterprises and Bashy & His Young Stars Orchestra. Be there in time to avoid rushing.

**Tickets: 4/- Flat**

Tickets now on sale at 3, Olushi Street Lagos 16, Bamgboṣe Street, Irohin Imọlẹ's Office Wẹmimọ Alakija 41 Denton Street, Ebute-Mẹtta.

BERE OJULOWO EGBOGI AWỌN FARANṢE TI NWỌN NPE NI-

**RICHELET**

FUN ARUN ẸJẸ ARA ENIA GBOGBO




Eleyi yato patapata si awọn Rọbi-rọbi. Iṣẹ rẹ lara eni si daju fun Iwosan gbogbo Kokoro buburu ti o ba wa ninu, ẸJẸ ARA bi Mọnmọnọ

Meji rẹ ko si ni gbogbo awọn Egbogi ti nwọn npe ni TỌNIKI Ẹjẹ ti nwọn si nta kaKiri ni owo pọọkuadimọwọ tabi ki o lọ nilẹ ko di owo Iyọn se ewọ, awa ki ta awọn egbogi ba wọn yẹn rara tabi ti nwọn npo ta ni lẹ yi.

Gẹgẹbi awọn Onibara wa ti mọ irufẹ awọn egbogi ba wọn yẹn a ma a ba ojulowo egbogi atata ti a ranṣẹ fun tita lati awọn ilu Jamani, Faraose ati ti awọn Tatambulu si Itali jẹ

Mọ daju pe, bi ẹjẹ ara ko ba mọ daradara awọn amodi tabi ailera wọnyi le se ọ, Lakuregbe, orisirisi Inarun, Oju ṣuju tabi didun, Jẹdijẹdi Akọ ba, arun Ẹdọki, Aya - didun pupọ ati Ekuru laya.

Ara riro, lapalapa, Egbo-Ẹs Amodi Apo ile itọ, ẹhin didun tabi ibaradi riro pẹlu Egbon RISALETI a ma a pa gbogbo kokoro buruku ti o wa nbo ẹje ara rẹ pata pata yio si ni ẹjẹ rẹ mọ tonitoni pẹlu.

Ṣa dan igo rẹ kan wo iwọ yio si ma a rohin rẹ fun ẹlomiran pelu.

Waterloo Medicine Store
8, Palm Church Street (Lagos.
Phone: 22878 Nigeria, Ọja Ita Faji)

# IROHIN IMOLE

IMOLẸ ỌRẸ AIYE, TẸNI GBOGBO LAWA

No. 576 FRIDAY, APRIL 10, 1964 (2D)


## Akiyesi Pataki Fun Gbogbo Enia

Lẹhinti mo ti ṣe abẹwo kakiri Ilẹ Naijiria ati Ghana, o dabi ẹnipe ọpọlọpọ enia ni nwọn nro wipe Iwe Irohin Imọlẹ ati Iwe Irohin Akintọla ti awọn npe ni Imọlẹ Owurọ ọkan na ni Iwe mejeji.

Eyi ki iṣe bẹ rara asi fẹ fi ye gbogbo enia ki o ye wọn wipe gedegbe ni Iwe Irohin Imọlẹ daduro ko faramọ ẹgbẹ oṣelu kankan ko si ni ohunkohun ṣe pẹlu Imọle Owurọ.

Iwe Irohin Akintọla ti nwọn ntẹ ni Ibadan ni ọngbẹnuṣe fun ẹgbẹ Akintọla Ibadan ni nwọn gbe ntẹ Imọlẹ Owurọ, Eko ni a gbe ntẹ Iwe Irohin Imọlẹ lati ọdun meje (1957) sẹhin.

A'o ṣe ifilọ yi lori Radio fun gbogbo enia lati gbọ, ṣugbọn ẹniti o ba tun fẹ alaye lori ọrọ yi le kọwe tabi ki o wa ri Alakoso Ile Iṣẹ Irohin Imọlẹ ni nọmba,

16, BAMGBOṢE STREET,
PHONE 21985, LAGOS.

# BABA KAN PE ALE ỌMỌ RẸ L'ẸJỌ !

IBADAN:- Ha ṣe gbogbo ero ti o pejọ si ile ejọ kekere kan ni ilu Ibadan nigbati ọdọmọbinrin kan omidan Bisi Ọladeji ti iṣe ọmọ ọdun mọkandinlogun nsọ jade pe ninu ọdun 1962 ni nwọn le on jade kuro ninu ile Iwe giga awọn Obinrin ti Idi-Aba ni ilu Abẹokuta.

Oni idi ti nwọn fi le na nipe on ti loyun. Ọdọ-on jade kuro ninu ile Iwe mọbinrin na Bisi Ọladeji ti on jẹri si ẹjọ kan ti Baba rẹ Ọgbẹni S. Mọgaji pe Ọgbẹni J. A. Adeniji ti nṣe oṣiṣẹ kan nilu Ọyọ.

Baba Bisi fẹ lati gba owo ẹgbẹta pọnun (£500) lọwọ Ọgbẹni Adeniji fun pe o gba ọna- ti ko tọ fun ọmọ on loyun ti o si tun di ọmọ na ni ọna lati kọ ẹkọ rẹ pari.

Agbẹjọro fun Baba Bisi tiṣe amofin Abiọdun Akerele fi han ile ẹjọ wipe Bisi lọ si ilu Ọyọ ninu ọdun 1962 lati lo isinmi ti nwọn gba nile-iwe ni o pade Ọgbẹni Adeniji yi.

O tun fi han wipe bi awọn mejeji ti pade ni nwọn ti nbara wọn sọrọ ti ọrọ na si bọ sii.

O tun sọ siwaju pe nibi ti nwọn ti nbara wọn ṣe faji ni oyun de ti o faa, ti Bisi ko fi le lọ si Ile-iwe mọ.

Adajọ ti sun gbigbọ ẹjọ na di ọjọ kejidinlogun oṣu yi. Ẹ o tun maa gbọ bi nwọn ba ti ṣe ẹjọ na si ninu Iwe wa.


## EGBOGI JẸDIJEDI

FUN EGBOGI



### "CYCLOVE"

Aworan oke yi fi han gbangba ibiti Jẹdijẹdi rẹ gbe wa lara id si nyọ ọ lẹnu nigbagbogbo. Ibẹ ni a npe ni "omusu tabi Iho rẹ enia ibiti a ma ngbe ṣe igbọnsẹ. Arun Jẹdijẹdi jẹ ọkan ninu amod ti o buru ni pataki fun Ọkunrin ti o si lagbara pupọ lati ṣe iwosan rẹ patapata.

Ọpọlọpọ egbogi ni nwọn nta kakiri lode nisiyi ti wọn a ma powo wọn fun iwosan rẹ ṣugbọn boya la leri mẹwa ninu ọgọrun ti o le ṣe iwosan arun yi daradara, Awọn ẹlomiran lero wipe boya bi wọn ba lọ si ile Dokita lati lọ ke eyiti o ba nyọ jade lati omusu ku ni pa bẹ awọn o bọ lọwọ rẹ patapata.

Ṣugbọn awa ko ro bẹ rara. Lẹhin ọdun diẹ iyọnu rẹ yio si tun bẹrẹ bakana. Orişirişi Jẹdijẹdi ni o wa ekini ti o bẹrẹ nipa aiko ma ṣe igbọnsẹ dede tabi lojojumọ, ẹlomiran nipa ijoko ni ojukanna ṣelu lojojumọ tabi gigun kẹkẹ ologere (Basikulu), pupọ ẹlomiran ewẹ nipa jijẹ Ṣuga tabi oniruru ohun adidun pupọju nigbakugba. Jẹdijẹdi orişirişi ni o wa, ewo ni tirẹ? Bi o nyọ jade ninu omusu, tabi ti o ba nmu ẹjẹ wa lẹhin igbọnsẹ, tabi ti o ba nyọ ti o ba ṣe igbọnsẹ tan ni, tabi ti orin ọ ninu omusu ni eyikeyi ti o ba ra bere egbogi "GYCLOVE" ti awọn Oyinbo Jamani ṣẹṣẹ wa idi rẹ a ki o si danwo orişi meta ni o daju wipe iwọ yio bọ lọwọ Jẹ dijẹdi na pata alafia yio de si ekeji rẹ ko si ninu gbogbo egbogid taara gboro ilu Naijiria jakejado. Bere rẹ ni:—

Waterloo Medicine Stores
8, Palmchurch Street, Lagos
Phone: 22878 Nigeria, (Oja Ita Faji)


## Ejọ Awo bẹrẹ Loni

Lati Oju Ewe Kini

jọ meje ni yio gbọ ẹjọ Olo ye Awolọwọ dipo Adajọ marun ti Ijọba ti yan lati gbọ ẹjọ na tẹlẹ.

Nigbati awọn Ọjọgbọn Amofin na de, ni a gbọ wipe Ijọba yio tun fi kun awọn adajọ ti yio gbọ ẹjọ na.

A gbọ wipe atamataṣe ogbonkangi agbẹjẹro ti o mọ nipa ofin ni awọn Agbẹjọro mejeeji na.

Ṣugbọn a ko ti ri i gbọ daju wipe nitori awọn ogbonkangi Agbẹjọro yi ni yio jẹki Ijọba sọ awọn adajọ di mejeje dipo marun ti o ti fẹ wa ninu Ile-ẹjọ na tẹ lẹ ri.

A ngbọ ni abẹlẹ wipe Ọlọla Clement Nagbọn de Lestang, ọkan ninu awọn adajọ agba Eko yio jẹ ọkan ninu awọn adajọ ti yio pẹlu ninu ijo ni Ile ẹjọ na ni ọla.

A tun gbọ ni abẹlẹ wipe gbogbo arin ilu ni awọn Ọlọpa yio ma rọngadi kiri lori ki ija o ma ba ṣe ṣẹlẹ nibikibi larin awọn ọmọlẹhin Oloye Awolọwọ.

Irohin kan tun fi ye wa pe awọn ọlọpa yio maa fun gbogbo awọn ti yio ba lọ woran ni kotu ni iwe aṣẹ ni oni ẹniti ko ba si ni iwe lọwọ ko ni le wọ inu Ile ẹjọ na.

Awọn oniwe irohin naapa yio gba iwe aṣẹ ki nwọn to le wọle, oniwe irohin Ejongboro ti gba iwe ni ọsan ana bi ẹjọ na ba si ti nlọ, ẹ o ma a gbọ.

A gbọ wipe ẹjọ na yio gba to oṣu meji ki nwọn o to le pari rẹ ti nwọn ba bẹrẹ ni owurọ yi.

Enia mẹtadinlogun ni Ijọba ju sẹwọn ni ọjọ kọkanla oṣu kẹsan ọdun ti o koja; ṣugbọn ọkan ninu awọn enia na, Sunmbọ Jibowu ti ku!

Oruko awọn Olujẹjọ na ni wọnyi:- Chief Ọbafẹmi Awolọwọ, Micheal Omishade, Gab Shashore, Akinsanya, Onitiri, Obietoma, Jibowu, S. T. Oredein, Okotiẹ - Yesin, Lateef Jakande, J. S. Ọlawọyin, Nwaobiala, Oyesile, Otubanjọ, Lawanson, Akamo, Umọren, Akinsanya.


Printed and Published by Modupe Printing Press 16, Bamgbose Street P O Box 1495 Phone 21985
Editor TUNJI ADEOSUN 4, Kadiri Street (C. M. S. Grammar School) Bariga Lagos (10/4/64)